Bọ́ síta, lọ kiri

Ayé kún fún àwọn ọ̀rọ̀ àti àwòrán àti nnkan tí ó yáni lára láti ṣe, fi ọwọ́ kàn wọ́n wo kí o sì yẹ̀ wọ́n wò, láti orí àwọn páálí onjẹ oníwóró àti àwọn pátákó ìgboro títí dé àwọn adágún omi kékeré tí ó ní ẹ̀rọ̀fọ̀ àti àwọn ewé tó ti jábọ́.

Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti ṣe àyẹ̀wò àyíká rẹ.

- Ẹ rìn jáde, kí ẹ sì sọ̀rọ̀ nípa àwọn lẹ́ta, ọ̀rọ̀ àti nọ́mba tí n bẹ lórí àwọn àkọlé oju-popo àti niwájú awọn ilé ìtajà
- Nígbà tí o bá nra ounjẹ, ṣe àfiwé títóbi, àwọn àwọ̀ àti òórùn àwọn èso àti ewébẹ̀

Njẹ́ o mọ̀ pé jíjáde láti rìn nṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọmọ rẹ láti kẹ́kọ̀ọ́. Maṣe yára rín ju ìgbésẹ̀ ọmọ rẹ lọ, sọ̀rọ̀ kí o sì fi ọkàn sí àwọn nnkan tí ó bá kíyèsí tabi tí o nbéèrè ibeere nípa rẹ̀.

Bí a ti nṣe tí a sì nlo àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ oní kaadi aláwòrán

Ohun tí o nílò
- Lẹ̀dì ìkọ̀wé àti beba fún àtòkọ ohun tí o fẹ́ rà
- Àwọn àwòrán èso àti àwọn ewébẹ̀
- Sisọ̀si ọmọdé tí kò léwu
- Ìlu ihò
- Òwú tàbí ohùn fún síso àwọn àwòrán náà papọ̀

Ohun tí o maa ṣe
Wá àkọsílẹ̀ èròjà ounjẹ kan kí o sí ṣe àtòkọ kan papọ̀ nípa gígé àwọn àwòrán àwọn èròjà láti ara àwọn ìwé ìléwọ́ àti ìwé àtìgbàdégbà.

Ṣe ìtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ kan nípa lílu ihò sí igun kan lára àwòrán kọ̀ọ̀kan kí o sì fi okùn kan so wọ́n pọ̀.

Jẹ́ kí ọmọ rẹ lo ìtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ náà nígbà tí o bá lọ rajà. Yóò ràn á lọ́wọ́ láti fi àwọn àwòrán náà wá ounjẹ. Ẹ jọ sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ẹ rí kí ẹ sì jọ ka iye tí ẹ nílò.

Olobó oníràwọ̀
Àwọn àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ oní kaadi àwòrán jẹ́ ọ̀nà pàtàkì láti bá ọmọ rẹ ṣeré. Gbìyànjú láti ṣe àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ ti àwòrán tí o lè rí nígbà tí o bá jáde tí o sì nrìn kiri.

Lọ́rọ̀ kúkurú
Nígbà tí o bá jáde tí o sì n rìn kiri pẹlu ọmọ rẹ, fetí sílẹ̀ sí àwọn ohùn tí o lè gbọ́, títí dórí àwọn ariwo ọkọ̀, fère orí ọkọ̀, orin, àwọn ajá tí ó ngbó, àwọn ẹyẹ tí ó nkọrin àti àwọn ọkọ̀ òfúrufú lókè. Sọ̀rọ̀ nípa ohun tí o gbọ́. Gbìyànjú kí o dún bí àwọn ohùn náà -- ṣé o lè dún bí awọn ohùn náà?